OWE
Ki a maṣe wo ti Pẹla
Bi a ba wo ti Pẹla
ijo a baje.

# Irohin Yoruba

VOL IX No. 449 MONDAY FEBRUARY 15, 1954 KOBO KAN (1d.)

E MA A POLOWO
Oja Nyin Sinu
Iwe Irohin Yoruba

# Adeleke Adedoyin Wo Egbe Action Group

Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin ṣe ipinnu pe on ti y'ọwọ yọ'ṣẹ ninu Ẹgbẹ N. C. N. C. on si fi ara mọ Ẹgbẹ Action Group (Ẹgbẹ Afẹnifẹre) lati di ọkan ninu ọmọ Ẹgbẹ na.

Alaye ti Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin ṣe ni pe ohun ti o mu ki on fi kuro n.nu Ẹgbẹ N.C.N.C. ni pe, aṣẹhinwa-aṣẹhinbọ o wa han si ohun gbangba pe Ẹgbẹ N. C. N. C. ki iṣe Ẹgbẹ ti o yẹ ọmọluwabi, nitoripe nwọn ko ni eto, bi nwọn ba pinnu pe inkan bayi ni awọn o bẹrẹ si ma a ṣe lati oni lọ ki ilẹ ọjọ keji to mọ, nwọn a ti tun mu omiran lati ṣe



Ọmọba Adeleke Adədoyin

Ọgbẹni ti o si jẹ Olori Ẹgbẹ N. C. N. C. Dokita Nnamdi Azikiwe ki i si fẹ gba imọran ẹnikẹni ti o ba ri wipe oye t'on pẹlu rẹ fẹrẹ jẹ dọgba-dọgba a fi ki o ma a fi han awọn gbaruku rẹ ti o ri pe nwọn ko ṣoro tẹ wipe ohun ti on ba ti ṣe nikan ni ki nwọn sa gba pe o dara, ko fẹ ijiyan ati atunṣe.

O si tun sọ wipe gbogbo inkan ti o dara fun eto ilu ti Ọgbẹni Alagba Herbart Macauley Ologbe) ni igba aiye rẹ nja fun, ninu Ẹgbẹ Dẹmọ igbana ni awọn Ẹgbẹ N. C. N. C. ti dori rẹ kodo ti nwọn si jẹ gaba lori Ẹgbẹ Dẹmọ ati wipe Azikiwe ko ni inu didun si idagbasoke Ilu abẹ Ijọba Iwọ-orun Nigeria.

Nitoripe gbogbo eto Action Group ti o ti ntako ni o wa pa ta fi ara mọ, sibẹsibẹ ko fẹ gba pe Ẹgbẹ Action Group ni eto ti o dara ju ti N. C. N. C. lọ. L'ọdun ti o kọja nwọn ṣe ofin pe ọmọ Ẹgbẹ N. C. N. C. ko gbọdọ ba awọn Ojotu Ijọba Gẹẹsi ṣ'ọrẹ, laipa ofin yi rẹ Azikiwe si ti nlọ jẹ ase apejẹ ni Afin Gomina l'Eko o si ti di wọlewọde Gomina - Kekere t'Ẹnugu.

L᾽k᾽ta, Ọmọ-Ọba Adeleke Adedo in pari ọrọ rẹ si w pe ẹnikẹni ti o ba fẹ sin ilu rẹ ni ọna ti o tọ, ati ọna ti ẹri ọkan rẹ yio fi da a lare ko wa sinu Ẹgbẹ Action Group.

# Esther Ko Ku Mo

Esther Johnson Ọdọmọde-birin ọlọdun mẹrindinlọgbọn ti o jẹbi apania, ti Adajọ Agba Adetokunbọ Ademọla da ẹjọ pipa fun ni Kotu nla Ibadan ni ọjọ kejidinlogun oṣu kẹfa ọdun ti o kọja yi ni Gomina yi idajọ na pada pe ki nwọn ma yẹgi fun un mọ ṣugbọn ki o kuku lo gbogbo ọjọ aiye rẹ ninu ẹwọn.

Eyi ni idajọa akọkọ ti Ile Igbimọ Gomina (Governor's Privy Council) kọ ṣe lati igbati Ọba-Obirin Ilu Oyinbo ti gori oye. Ninu oṣu kẹwa ọdun ti o kọja yi ni Obirin na Esther Johnson kọwe ẹbẹ si Igbimọ Idajọ Gomina na pe ki nwọnjọwọ dari jin on ki ẹjọ pipa ti Adajọ ti da fun on ma ba a ṣẹ.

Ohun ti o fa sababi ti Esther Johnson fi pa Ọgbẹ ni Maurice Hall Oyinbo oniṣẹ Reluwe yi ni Ibadan ni pe Oyinbo yi ba ti ṣe adehun a ti gbe e ni Iyawo nitoripe nwọn ti nfẹ ara wọn ti pẹ, ki o si mu u lọ han awọn ẹbi rẹ ni ilu Oyinbo lọhun.

Ṣugbọn nigbati Oyinbo yi gba isinmi lọ sile ni ilu rẹ ti o pada de Ibadan ni o sọ fun Esther pe adehun on pẹlu rẹ ko bọsi mọ, on ti fẹ obirin-Oyinbo kan ni ile, on si ti gbe e ni arede, laipẹ yio de si ilẹ yi (Ibadan) nitorina ki Esther mu ọkan kuro ninu adehun pe on yio tun fẹ ẹ mọ tabi lati tun gbe e ni Iyawo-alarede mọ.

Ṣugbọn Oyinbo na sọ fun Esther pe iyẹn ko di i lọwọ lati sun ni ọdọ on ki awọn si ṣe faaji mọju,



ESTHER JOHFSON

ni Esther ba lọ ra ọbẹ pamọ ki nwọn to sun. Nigbati o di afẹmọjumọ ọjọ na ni o ba gun Oyinbo na ni ọbẹ lati oju orun, ni oyinbo na ba fi bẹẹ ku bam-bam.

Ni Esther wa fi ẹnu ara rẹ jẹwọ fun awọn Ọlọpa ni ṣọbu Ọlọpa (Police Station) li Eko. Lẹhin ti o gba idajọ iku, o tun gbe ẹjọ rẹ lọ si Kọtu Nla Alaga-Mẹta (West African Court of Appeal). Ni ọjọ keji oṣu kẹwa Ọdun ti o kọja ni nwọn kọ ẹjọ rẹ ni Kọtu Alaga mẹta na, ki o to gbe e wa siwaju Igbimọ Idajọ Gomina (Governor's Privy Council). Bayi ni ẹjọ rẹ pari si.

## Lemomu Agba Jalaisi

EKO – Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Lemọmu Agba Ahmed Tijani Ibrahim ti iṣe Lemọmu Mọṣalaṣi Jumọ Eko jalaisi ninu ile rẹ ni Victoria Street l'Eko, nigbati o di ẹni ọdun mejileladọrin, ti o si ti ṣe ailera fun igba diẹ. Nwọn sin in ni ọjọ keji ti o ku ni agogo mẹwa abọ arọ sinu Mọṣalaṣi Jimọ na, Alfa Amuṣa Senu ni o ṣe isin isinku na ninu ile oku na ati ninu Mọṣalaṣi ti nwọn sin in si, awọn Lemọmu ti Mọṣalaṣi kekeke si ran an lọwọ.

O to ẹgbẹdogun awọn Musulumi pataki pataki ti ilu Nigeria ti o wa si ibi isinku na. Alhadji Salmon Danmọle, Olori awọn -Alhadji Eko ni o ṣiwaju awọn Alhadji ti nwọn gbe oku jade lati inu ile rẹ (oku) lati sinin. Lemọmu na jẹ ọmọluwabi, ọmọ mẹtala l'ọkunrin l'obirin si ni o gbẹhin rẹ. Ọlọrun ko dari ọṣẹ rẹ jin in, ki O si jẹ ki ẹhin rẹ o dara.

E MA A KA
IWE
Irohin Yoruba

## Paul Oladosu Jalaisi

TARKWA- G.C. Ni alẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Paul Oladosu ti ile Ọbale Ọyan ku ni ilu Tarkwa G. C. nigbati o di ẹni ọdun mọkanlelogọta laiye. Awọn ijọ Ẹlẹri Jehofa ati awọn ọmọ Ile - Obale ti o wa ni Oke-okun ati Ẹgbẹ "Ilọsiwaju Ọyan wu mi" sin oku na lọna ti Onigbagbọ. Ọgbẹni Daniel Ọkẹ si ṣe gudugudu meje nibi isinku na.

Ero pọ nibi isinku na bi omi, eyi fi han bi Oloye na ti gbajumọ to ati bi o ti ṣe

Wo oju ewe kẹrin

REDIFFUSION
FOR LESS THAN THREEPENCE PER DAY
you can obtain
NEWS
MUSIC
EDUCATION
ENTERTAINMENT
FROM 6 A.M. to 11 P.M.
IN YOUR OWN HOME
APPLY AT OFFICES IN LAGOS, IBADAN & ILESHA.

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Idahun si ibere Elefole

EYI ni idahun ti Ogbeni Joseph Elefola, Orthopaedic Hospital, Igbobi fi sowo funra ara re fun itumo ibere re ti o jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti 7/12/53 eyiti awon Ogbeni Job. B. Bamgboye, Iludun leba Offa, Awoko Jesu, Ibadan ati Michael Babatunde Driver 40 Popo Street Oshogbo ninu Iwe ti 11-1-54.

Olotu, ki nto bere si se alaye Idahun ibere mi na gege bi oye ibere mi na ti ye mi de ninu Bibeli, mo fe dupe pupo lowo awon ti o tete dahun si ibere mi na ninu Iwe Irohin Yoruba ti 11 1/54. Ki Olorun bukun ogbon ati lakaye won.

Gege bi idahun si ibere na ti lo si niyi:-

1. Irinwo odun o le ogbon. Eksodu 12 : 40.

2a. Awon Maria mefa.(1) Maria Iya Jesu, (2) Maria Magdalene, (3) Maria Iya Jakobu, (4) Maria keji, (5) Maria Iya Jose, ati (6) Maria aya Klopa. Ibiti a ti le ri won ka niwonyi:- (a) Matteu 1 : 18. (b) Matteu 27 : 56. (d) Matteu 28: 1. (e) Marku 15 : 47 ati (e) Johannu 19 : 25.

2b. Marun (1) Josefu Omo Israeli, (2) Josefu oko Maria, (3) Josefu ara Arimatea, (4) Josefu Ibatan Maria ati (5) Josefu Barnaba. Ibiti a ti le ri won ka niwonyi:- (a) Genesisi 37 : 3 (b) Matteu 1 : 16. (d) Matteu 27 : 57. (e) Luke 3 : 26. ati (e) Ise Awon Aposteli 4 : 36.

3. Michael, Gabriel, Raphael, ati Oriel.

4. Jesu Kristi ni Olorun ba so oro na. Johannu 1 : 1 - 3.

5 O pari ise re nipa ti ara li aiye, sugbon ki se nipa ti emi. John 19. 28.

6a. Awon meji ni, Isaaki ati Josefu.

6b. Isaaki omo Abrahamu teriba fun iku. Genesisi 22 : 9-10. Gege bi ti Jesu Kristi Oluwa wa. Mattew 26:50-53. Nwon ta Josefu gege bi won ti ta Jesu Kristi Oluwa wa. Jesu Kristi ko gbesan lara awon Ju; beni Josefu si lagbara lati gbesan lara awon arakunrin re, ko si gbesan gege bi ti Jesu Kristi Oluwa.

7 Iwo li eniti mbo tabi ki a ma a reti elomiran? Mattew 11:3.

8 Lusiferi. Sugbon Irawo Owuro ati Kerubu ki ise oruko Angeli kan soso. Oruko ti Esu koko je pataki ni Lusiferi. Isaiah 14:12. Ezekiel 28:14.

9a. E ma sokun fun mi, sugbon e sokun fun ara nyin ati fun awon omo nyin. Nitorina e kiyesii, ojo mbo li eyiti enyin o wipe. "Ibukun ni fun agan, ati fun inu ti ko bimo ri, ati fun omu ti ko funni mu ri. Luku 23:28-29.

9b. Nitori ti awon ti o soro ki ise ti Jesu Kristi Oluwa wa.

10a. Ifihan 6 : 16.
Josua ni.

10b. Nigbati awon omo Israel ko duro deje pelu ofin Olorun. Josua 24:15.

11 Olori-oko oju omi ni o so oro na si woli Jona. Jona 1:6.

Olotu, mo dupe aye ti e gba mi o! Olorun Olodumare yio ma a ran nyin lowo ninu gbogbo eto ati sise nyin. A nin.

Emi ni ti nyin
ninu Oluwa,
Joseph Elefola
Omo Owo
Orthopaedic Hospital
IGBOBI

AKIYESI -- Awon meji ti oruko won wa ni isale yi ni o tun fi idahun Ibere Elefola na sowo, sugbon o pe ki a to ri i gba. nwon gbiyanju sa a. Awon na ni:-

1. Ade Adesina
Toroko - Bida - Road
ati David Ade Adediran
Baptist Church
Keffi.

E ku ise o.

OLOTU



Posi oku Lemomu Ibrahim ni awon A'afa duro ti yi.

### Oba Adele keji se Kisa

(Lati oju ewe keji)

apere rere fun enikeni ti o ba wa ninu iru ipo be ninu awon Oba ile wa lati se afarawe re.

Ade a pe lori, Bata a pe lese Oba o. E o lo aye na pe o.

ADINWO-IWE-YI-KU

Lati 7/6d si 5/6d.
Iwe Egbogi
OTITO FERO
Iwosan ati Odu Ifa.
E wa ra a lowo:-
LIADI A. IBIWUNMI,
46, Moloney Bridge Street,
LAGOS.

Jeki Irora Na Lo

"Mentholatum" ma nmu irora kuro lara were bi idan.

Bi o ba ti fi pa ibi ti o ndun e were ni yio si bere si pa etu si i, o rorun lo gbaje lati lo Mentholatum. Sa fi pa ibi ti o ndun e irora ra yio si lo. Ko si ohunkohun ti o fe se ju pe ki o fi pa ibe lo. Majafara lati lo ra "Mentholatum" fun anfani re, o dara ju gbogbo ogun irora lo.



TETE BO NINU IRORA

Bere Fun Men-tho-la-tum





Ti o wa ninu ago lo ati ide.
Eyi ti o je pe Awon The "Mentholatum" Co, Ltd. (1st. 1889) Slough England nikan ni o nse e.

MENTHOLATUM

Tete wo iko re san




Bi iko ba nfin e ni ona-ofun ti ko si jeki o sun l'ale, mu iwon iba Veno's die ki o to sun.

Ti o ba di e ni aiya ti o si fun e ni inira mu Veno's, lesekese ni wa ti ri irorun ati itura.

Bi o ba ti d'ogbe si e ni ona ofun, gbogbo re ni Veno's yio mu kuro.

Fi Veno's si arowoto re fun lilo awon omo ati aya re, iba se omode tabi agbalagba. Tete lo ra igo kan loni.

Sa Mu VENO'S LIGHTNING COUGH MIXTURE

